# SISẸ́ JESU ATI IDAJỌ ÈKÉ TI A ṢE FUN UN

**Matteu 26:47-68; 27:1, 2, 11-26**

**ẸKỌ 431 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: "A jẹ ẹ ni iyà, a si pọ́n ọ loju, ṣugbọn on kò yà ẹnu rẹ̀: a mu u wá bi ọdọ-agutan fun pipa, ati bi agutan ti o yadi niwaju olurẹ́run rẹ̀, bẹ̃ni kò yà ẹnu rẹ̀" (Isaiah 53:7).**

**I A Mú Jesu ni Wakati Oru**

1 A rán ọ̀pọ eniyan pẹlu idà ati ọ̀gọ lati mú Jesu, Matteu 26:47

2 Judasi fi ifẹnukonu fi Jesu hàn, Matteu 26:48-50

3 Peteru fa idà yọ, o si gé eti Malku, Matteu 26:51-56; Johannu 18:10

**II Idajọ Ọganjọ Oru ati Owurọ niwaju Ajọ Igbimọ Awọn Ju**

1 Ni oru ni a ṣe idajọ Jesu kin-in-ni niwaju Kaiafa, Matteu 26:57-68

2 Ni owurọ ni a ṣe idajọ Jesu lẹẹkeji niwaju Kaiafa, Matteu 27:1; Marku 15:1; Luku 22:66-71

**III Awọn Idajọ Mẹta niwaju Baalẹ Romu**

1 Idajọ kin-in-ni ti Pilati ṣe ni pe, "Emi kò ri ẹ̀ṣẹ lọwọ ọkunrin yi," Matteu 27:1, 2, 11-14; Luku 23:1-5

2 Hẹrọdu ri i pe Jesu kò ṣe ohun kan ti o yẹ si ikú, Luku 23:6-11, 15

3 Nigba ti a mú Jesu wá siwaju Pilatu lẹẹkeji o wá ọna lati dá A silẹ, Matteu 27:15-23; Luku 23:13-20; Johannu 19:12

4 Ariwo ijọ awọn eniyan bori, Matteu 27:24-26

## ALAYE

**Eto**

Ni ọjọ meji ṣaaju Ajọ Irekọja, awọn olori alufaa, awọn akọwe ati awọn agbaagba ti pejọ pọ̀ ni aafin Kaiafa, olori alufaa, lati gbero bi wọn yoo ti ṣe le pa Jesu lai si ariwo awọn eniyan. Gẹrẹ lẹyin eyi ni Judasi ṣe adehun pẹlu awọn olori alufaa, o si gbà lati fi Jesu hàn fun ọgbọ̀n owo fadaka gẹgẹ bi asọtẹlẹ Sẹkariah: "Mo si wi fun wọn pe, Bi o ba dara li oju nyin, ẹ fun mi ni owo-ọ̀ya mi: bi bẹ̃kọ, ẹ jọwọ rẹ̀. Bẹ̃ni nwọn wọ̀n ọgbọ̀n owo fadakà fun iye mi" (Sẹkariah 11:12). Lati igba naa lọ ni Judasi ti n duro de akoko ti yoo fi Jesu hàn. Ni oru ọjọ Ajọ Irẹkọja Jesu nikan wà pẹlu awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ mejila. Akoko ti Judasi n duro de ni eyi. Kristi ti sọ fun un pe oun ni ẹni ti yoo fi Oluwa rẹ̀ hàn, ṣugbọn eyi kò da a duro. Gẹgẹ bi aṣaaju awọn ọpọ eniyan ti o di ihamọra ti awọn olori alufaa ti fi fun un, Judasi wi pe, 'Alafia, Olukọni," o si fi ẹnu ko Jesu ni ẹnu.

**Idajọ Ekinni**

Bi o tilẹ jẹ pe òru ni, sibẹ awọn akọwe ati awọn agbaagba pejọ pọ̀ lati gbero bi wọn yoo ṣe pa Jesu. Awọn eniyan wọnyii, lai si aniani, jẹ́ diẹ ninu igbimọ awọn Ju, ti a n pè ni Sanhẹdrin, eyi ti i ṣe ile-ẹjọ giga awọn Ju. O lodi si ofin fun ajọ igbimọ yii lati pejọ ni òru, ṣugbọn nihin wọn n joko fun idajọ Ọkunrin naa ti wọn ti di ọtẹ si. Nitori ti wọn ti ni ohun kan ninu si Kristi tó lati sọ wọn di alaiyẹ lati ṣe idajọ Rẹ̀. O fẹrẹ jẹ pe ohun gbogbo ti ajọ naa ṣe lati ṣe idajọ Jesu ni o lodi si ilana ti awọn paapaa duro lé lori.

Wọn kó awọn ẹlẹri eke jọ ki wọn ba le sun Jesu lẹsun ni ile ẹjọ, ṣugbọn o tilẹ ṣoro lati ri ẹlẹri meji ti ọ̀rọ wọn ṣe deedee. "Nikẹyin li awọn ẹlẹri eke meji wá; Nwọn wipe, Ọkunrin yi wipe, "Emi le wó tẹmpili Ọlọrun, emi o si kọ́ ọ ni ijọ mẹta" (Matteu 26:60, 61). "Ati ninu eyi na pẹlu, ohùn wọn kò ṣọkan" (Marku 14:59). Niwọn bi ọrọ awọn mejeeji wọnyii kò ti dọgba, ẹri wọn kò ṣanfaani gẹgẹ bi Ofin. "Li ẹnu ẹlẹri meji, tabi ẹlẹri mẹta, li a o pa ẹniti o yẹ si ikú; ṣugbọn li ẹnu ẹlẹri kan, a ki yio pa a" (Deuteronomi 17:6). Jesu gbọ́ bi awọn ẹlẹri èké wọnyii ti n sun Oun lẹsun, ṣugbọn kò ya ẹnu Rẹ̀ lati sọ

ọ̀rọ kan. "A jẹ ẹ ni iyà, a si pọ́n ọ loju, ṣugbọn on kò yà ẹnu rẹ̀; a mu u wá bi ọdọ-agutan fun pipa, ati bi agutan ti o yadi niwaju olurẹ́run rẹ̀, bẽni kò yà ẹnu rẹ̀" (Isaiah 53:7).

Ofin awọn Sanhẹdrin (Ajọ Igbimọ awọn Ju) kò gbà fun ẹnikẹni ninu wọn lati jẹ́ olufisun. Ṣugbọn ọwọ ẹsùn ni olori wọn, ani olori alufaa, yọ nigba ti o wi pe, "Mo fi Ọlọrun alãye fi ọ bu pe, ki iwọ ki o sọ fun wa bi iwọ ba ṣe Kristi Ọmọ Ọlọrun" (Matteu 26:63). Nigba ti a ti fi I sabẹ ibura bayii, Kristi fesi, O si wi pe "Iwọ wi i". Idahun Jesu ninu iwe Marku ni pe "Emi ni". O lodi si ofin ki a sọ eniyan kan di arufin nipa ẹri ara rẹ̀. Nipa fifi agbara mú Jesu labẹ ibura lati fesi ibeere yii, wọn fi agbara mu Un lati jẹri ni, ki wọn ba le sọ Ọ di arufin.

Gbogbo wọn fi ohùn ṣọkan lati dá Jesu lẹbi blasfeme, ati pe o yẹ si ikú, nitori pe o fi ẹnu ara Rẹ̀ jẹwọ pe Oun ni Kristi, Ọmọ Ọlọrun. A ko le pe ohun ti Jesu wi ni blasfeme, ayafi bi ẹri ba wà pe Oun ki i ṣe Messia. Wọn ko tilẹ gbiyanju lati wadii wò bi ọrọ Rẹ̀ ki ba i ṣe otitọ. Gẹgẹ bi ofin awọn Ju, a fi ye ni pe, ọ̀kan ninu awọn adajọ ni lati ṣẹnu fun ẹni naa ti a fi ẹsun sùn, adajọ yii si ni lati wi pe ẹlẹjọ naa kò jẹbi. Bi a ba pa ẹnu pọ wi pe arufin kan jẹbi ninu ẹjọ ipaniyan, idajọ naa ko le duro nitori a kò ṣẹnu fun arufin naa. Nipa bayii ẹjọ akọkọ ti a dá fun Jesu ko fẹsẹmulẹ, nitori (lọna kin-in-ni) gbogbo awọn adajọ ni o pa ohun pọ̀ pe O jẹbi; (lọna keji) kò si awọn ẹlẹri meji ti ọrọ wọn jẹ bakan naa; (lọna kẹta) ẹsun blasfeme ko le duro nitori nipa ẹri ara Rẹ̀ pe Ọmọ Ọlọrun ni Oun, ni a ṣe fi ẹsun sun Un, a ko si ri ẹri kan ti o sọ pe Oun ki i ṣe Messia.

**Idajọ Keji**

Gẹgẹ bi ilana ofin fun ẹjọ lile, a ko le ṣe idajọ ikú bi ko ṣe pe a ba ti mu arufin naa wá si ibi idajọ nigba meji. Alafo ọjọ kan gbọdọ wà laaarin igba mejeeji. Lati pa ofin mọ́, wọn duro di ojumọ ki a to bẹrẹ si ṣe idajọ keji fun Jesu. Wọn kò wadii ọrọ lẹnu ẹlẹri kankan, nipa bayii, ile-ẹjọ tún rú ofin nigba ti a tun n beere lọwọ Jesu ki o jẹri lodi si ara Rẹ̀. Ko si adajọ ti o gba ẹjọ Rẹ̀ rò. Ifohunṣọkan lati dá ẹjọ ẹbi fun Jesu ko fẹsẹmulẹ nitori ko si ẹni ti o ṣe ẹnu fun Un. Dipo ti wọn i ba fi da A lare, a dá Jesu lẹbi ikú nitori a da A lejọ pe o jẹbi blasfeme.

Bi o ba ṣe pe igbimọ awọn Ju (Sanhẹdrin) ni aṣẹ lati mu idajọ yii ṣẹ, lẹsẹkẹsẹ ni wọn i ba sọ Jesu lokuta pa. Ijọba Romu fi àye silẹ fun ile ẹjọ awọn Ju lati maa bojuto ọran ilu ati ẹsin wọn, ṣugbọn wọn ni lati mu ọran ti o ba jẹ mọ iyè ati ikú tọ Baalẹ Romu lọ. Ile-ẹjọ awọn Ju ti ṣe idajọ ikú ti wọǹ ko lẹtọ lati ṣe tabi lati muṣẹ. Agbara Ajọ Igbimọ awọn Ju (Sanhẹdrin) ninu ọran yii ko ju pe ki o mu ẹsun naa wá siwaju Baalẹ Romu.

**Ninu Itimọle**

Nigba ti Jesu wà ninu itimọle Igbimọ awọn Ju, iwa ti o tọ́ ni o yẹ ki wọn hù si I, ṣugbọn yatọ si eyi, iwa abuku ni wọn hu si I - wọn tutọ si I lara; wọn si kan An lẹṣẹ. Ohun ti wọn ṣe yii lodi si ofin, o si tun rẹ iyì ile-ẹjọ ti o ga ju ni orilẹ-ede Ju silẹ. Isaiah sọ asọtẹlẹ nipa ihuwasi yii: "Mo fi ẹ̀hìn mi fun awọn aluni, ati ẹ̀rẹkẹ mi fun awọn ti ntú irun: emi kò pa oju mi mọ́ kuro ninu itìju ati itutọ́ si" (Isaiah 50:6). Nigba pupọ ni a n tọka si Agbelebu gẹgẹ bi apẹẹrẹ iyà Jesu fun wa, ṣugbọn pupọ ni iyà ti o jẹ ki o to de ori agbelebu. "Ṣugbọn a ṣá a li ọgbẹ nitori irekọja wa, a pa a li ara nitori aiṣedede wa; ìna alafia wa wà lara rẹ̀, ati nipa ìna rẹ̀ li a fi mu wa lara da" (Isaiah 53:5).

**Niwaju Pilatu**

Nigba ti Igbimọ awọn Ju (Sanhẹdrin) ti dajọ ikú fun Jesu nitori blasfeme, wọn de Jesu, wọn si mu Un wá siwaju Pilatu, Baalẹ ti i ṣe onidajọ Romu. A le ri idajọ ẹ̀sin ti a ṣe fun Jesu ni kikun bi a ba ṣe akiyesi ohun ti a fi Jesu sùn si niwaju Pilatu. Wọn gbagbe ẹsun iṣaaju pe o jẹbi blasfeme. A si fi ẹsun iditẹ si Ijọba Romu sun Jesu. Ẹsun iditẹ yii yoo mu ki Pilatu fetisi ọran wọn, nigba ti o ṣe pe ẹsun blasfeme ko le tà niwaju Rẹ̀, nitori blasfeme kò si ninu ofin Romu. "Wọn si bẹ̀rẹ si ifi i sùn, wipe, Awa ri ọkunrin yi o nyi orilẹ-ede wa li ọkàn pada, o si nda wọn lẹkun lati san owó-ode fun Kesari, o nwipe on tikara-on ni Kristi ọba" (Luku 23:2). Iru ẹsun eke wo ni eyi i ṣe ti a ba fi we ọrọ Jesu ti o wi pe, "Njẹ ẹ fi ohun ti iṣe ti Kesari fun Kesari" (Matteu 22:21). Pilatu ṣe idajọ kin-in-ni pẹlu awọn ọrọ wọnyii, "Emi kò ri ẹ̀ṣẹ lọwọ ọkunrin yi" (Luku 23:4).

**Niwaju Hẹrọdu**

Nigba ti Pilatu gbọ́ pe lati Galili ti o wà labẹ akoso Hẹrọdu ni Jesu ti wá, Pilatu rán Jesu lọ sọdọ rẹ̀. Niwaju Hẹrọdu "Awọn olori alufa ati awọn akọwe duro, nwọn si nfi i sùn gidigidi" (Luku 23:10); ṣugbọn Hẹrọdu kò ri ẹ̀ṣẹ kan lọwọ Jesu. Bi o tilẹ jẹ pe a dá Jesu lare, sibẹ "Hẹrọdu ti on ti awọn ọmọ-ogun rẹ̀, nwọn kẹgan rẹ̀, nwọn si nfi i ṣẹsin, nwọn wọ̀ ọ li aṣọ daradara, o si rán a pada tọ̀ Pilatu lọ" (Luku 23:11). Eyi jẹ́ idalare keji ni ile-ẹjọ Romu.

**Niwaju Pilatu Lẹẹkeji**

"Nigbati Pilatu si ti pè awọn olori alufa ati awọn olori ati awọn enia jọ, o sọ fun wọn pe, Ẹnyin mu ọkunrin yi tọ̀ mi wá, bi ẹni ti o npa awọn enia li ọkàn dà; si kiyesi i, emi wadi ẹjọ rẹ̀ niwaju nyin, emi kò si ri ẹ̀ṣẹ lọwọ ọkunrin yi, ni gbogbo nkan wọnyi ti ẹnyin fi i sùn si: Ati Hẹrọdu pẹlu: o sá rán a pada tọ̀ wa wá: si kiyesi i, ohun kan ti o yẹ si ikú a ko ṣe si i ti ọwọ́ rẹ̀ wá. Njẹ emi o nà a, emi ó si jọwọ rẹ̀ lọwọ lọ" (Luku 23:13-16). Pẹlu awọn ọrọ wọnyii, Pilatu sọ ọrọ idajọ rẹ̀ keji pe Jesu "kò jẹbi."

Bi o ba ṣe pe Pilatu paapaa jẹ́ oloootọ eniyan, oun i ba duro ti ọrọ rẹ̀, i ba si dá Jesu silẹ. Dipo eyi, ariwo awọn ijọ eniyan bori. "Pilatu si fi aṣẹ si i pe, ki o ri bi nwọn ti nfẹ" (Luku 23:24). Nipa iṣe Pilatu yii, o ru ofin rere ilẹ Romu nì ti o sọ bayii pe: "Adajọ kò gbọdọ fetisi ariwo ọpọ ero lati gbé are fun ẹlẹbi tabi lati gbé ẹbi fun alare."

Ṣugbọn ju rirú ofin awọn Ju ati ti Romu, Pilatu rú ofin Ọrun ni ti pe o du Ẹni naa ni idajọ ododo, Ẹni ti oun paapaa wi nipa rẹ̀ pe "Emi kò ri ẹ̀ṣẹ kan lọwọ rẹ̀" (Johannu 18:38), ati nipa fifi I le ọwọ awọn ọta Rẹ̀ lati kan An mọ agbelebu, o bẹru ibinu eniyan ju ibinu Ọlọrun lọ. Bayii ni a si mú Ọrọ Ọlọrun ṣẹ, eyi ti o wi pe: "Awọn ọba aiye kẹṣẹ jọ, ati awọn ijoye ngbimọ pọ̀ si OLUWA ati si Ẹni-ororo rẹ̀" (Orin Dafidi 2:2).

## AWỌN IBEERE

1. Sọ diẹ ninu awọn ọna ti idajọ Jesu fi lodi si ofin?
2. Ta ni gé eti iranṣẹ olori alufaa?
3. Awọn asọtẹlẹ Majẹmu Laelae wo ni a muṣẹ ninu ekọ yii?
4. Darukọ oriṣiriṣi awọn alaṣẹ ti a mú Jesu wá sọdọ rẹ̀?
5. Agbegbe wo lo wà labẹ akoso Pilatu?
6. Hẹrọdu mẹrin ni a darukọ ninu Majẹmu Titun. Akọsilẹ miiran wo ni o wà nipa Hẹrọdu yii? Nibo ni agbegbe rẹ̀?
7. Lori ki ni igbimọ awọn Ju dá Jesu lẹbi?
8. Awọn ẹsun wo ni a fi Jesu sùn si niwaju Pilatu?
9. Njẹ Pilatu dá Jesu lẹbi?
10. Ki ni ṣe ti Pilatu ṣe fi àye silẹ pe ki a kan Jesu mọ́ agbelebu?